Ẹnikẹni ninu yin o gbọdọ fi ọwọ ọtun rẹ mu nkan ọmọkunrin rẹ nigba ti o ba n tọ, ko si gbọdọ fi ọwọ rẹ ọtun ṣe imọra nibi igbọnsẹ, ko si gbọdọ fẹ ategun si inu ife imumi

Lati ọdọ Abu Qatāda- ki Ọlọhun yọnu si i - o sọ pe: Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - sọ pe: «Ẹnikẹni ninu yin o gbọdọ fi ọwọ ọtun rẹ mu nkan ọmọkunrin rẹ nigba ti o ba n tọ, ko si gbọdọ fi ọwọ rẹ ọtun ṣe imọra nibi igbọnsẹ, ko si gbọdọ fẹ ategun si inu ife imumi».

[O ni alaafia] [Ohun ti wọn fi ẹnu kò lé lórí ni]

Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ṣàlàyé awọn ẹkọ kan; nigba ti o kọ ki ọkunrin fi ọwọ ọtun rẹ gba oko re mu nigba ti o ba n tọ, ati lati mu ẹgbin kuro niwaju tabi ẹyin pẹlu ọwọ rẹ ọtun; nitori pe ọwọ ọtun wọn pese rẹ fun awọn iṣẹ rere ni, Gẹgẹ bi o ṣe kọ fun ọmọniyan lati mi sinu igba ti o fẹ mu nibẹ.

https://sunnah.global/hadeeth/yo/show/3079

النجاة الخيرية
ALNAJAT CHARITY
لجنة الدعوة الإلكترونية
EDC E-Da'wah Committee